*YORUBA "Who will deliver me?"*

# TANI YIO GBA MI ?

Ni ọjọ isimi kan mo nwasu ihinrere iyanu ti Kristi ni ileto ojoye kan ni Basutoland. Ọpọlọpọ enia, ati Oloye ileto yi pẹlu iyawo rẹ pejọ lati gbọ ọrọ Ọlọrun. Orọ Ọlọrum ti o ye ti o si lagbara, ti o mu ju ida oloju meji lọ yi mu ki ọkan gbogbo awọn enia ti o pejọ si ibi ipade yi gbọgbẹ gidigidi.

Bi mo ti nba iwasu ọrọ yi lọ, iyawo Oloye nla yi, ati AYABA, bẹrẹ si sọkun kikoro. Pẹlu omije to nsan lati ẹrẹkẹ rẹ, o dide duro o si kigbe soke wipe, "TANI YIO GBA MI?" Jọwọ ran mi lọwọ, ọkan mi bajẹ gidigidi, Emi jẹ aboṣijulọ ati ẹni egbe. TANI LE RAN MI LỌWỌ? TANI YIO GBA NINU IRA ATI IDE ẸṢẸ? KINI OHUN TI KI EMI ṢE? Gbogbo nyin patapata lati oke de ilẹ ni ẹ mọ iru ẹni ti mo jẹ, Emi ni iyawo [AYABA] Oloye nyin, mo si jẹ ọkan ninu awọn obinrin ti o nkun fun adura, mo wa ninu ẹgbẹ obinrin aladura.

TANI YIO GBA MI?



ẸNITI O NDẸṢẸ TI EṢU NI. JOHANNU 3:8.

Fun nkan bi ogun ọdun ni mo ti nlọ si ṣọṣi, ṣugbọn eyi ko jẹ iranlọwọ fun mi rara, wọn ko le sọ mi di ominira, ẹṣẹ ti de mi ni igbekun. ỌMUTI paraku ati apania ni mo jẹ. Ọwọ mi kun fun ẹjẹ ati iwa ika, kiṣe ohun rere bikoṣe ki o ma mu ọti biya, ọti egun ni BIYA jẹ. Ẹṣẹ de mi ni ọwọ ati ẹsẹ, mo wa di ẹlẹwọn ọrun apadi!"

Arabinrin yi sọkun kikoro, o joko, o si ki gbe lohun rara wipe "Ran mi lọwọ! Ran mi lọwọ! Tani yio gba mi? Tani yio gba mi ninu ṣẹkẹṣẹkẹ ẹṣẹ yi? Mo fẹran Ọlọrun, ṣugbọn ẹṣẹ lo njọba lọkan mi, ẹṣẹ yi bẹrẹ si fa mi lọ si Ọrun Apadi. Emi ni mo pa akọbi mi okunrin ni kekere, mo ti mu ọti yo nigbati mo pọn ọmọ mi yi si ẹhin mi, Ọti yi mu ki oju mi ranko mo bẹrẹ si yi gbirigbiri ni ilẹ pẹlu ọmọ lẹhin mi titi mo fi fi ori ọmọ mi gba okuta, o si ku. Jọwọ ran mi lọwọ, yọ mi kuro ninu ajaga iku yi. Gbogbo iwa ibọriṣa ko ran mi lọwọ. Ẹsin mi ko ran mi lọwọ. Tani le ran mi lọwọ? TANI YIO GBA MI"?

Mo wa da lohun mo wipe. "ALAFIA NI FUN Ọ." Ma ṣe sọ ireti nu rara. Ohun ti o nda ọ lamu yi ni ohun ti o ndamu olukuluku enia, kiṣe iwọ nikan. IWE ỌLỌRUN, ti ṣe BIBELI fun ọ ni idahun ohun ti nba ọkan rẹ jagun. ROMU 7:15-25, sọ fun wa bi ẹṣẹ ti ṣe njọba lọkan wa, bakanna ni o si tun tọka wa si ẸNIKAN ti o ni agbara lati da wa nide lati gba wa silẹ.

Nitoriti mo mọ pe ninu ara mi ko si ire kan nibẹ, emi fẹ ṣe rere ṣugbọn emi ko ni agbara lati ṣe rere yi. Rere ti o tọ ki emi ko le ṣe, ṣugbọn ibi ti emi ko fẹ ni emi nṣe. Ẹmi ẹṣẹ ti o ngbe inu mi ni o nti mi lati ma ṣe buburu nigbagbogbo eyi ko si fun mi ni aye lati ṣe rere ti emi fẹ ṣe. Inu mi sa dun si ofin Ọlọrun nipa ẹni ti inu, ṣugbọn mo ri ofin miran ninu awọn ẹya ara mi, ti mba ofin inu mi jagun ti o si ndi mi ni igbekun wa fun ofin ẹṣẹ, ti o mbẹ ninu awọn ẹya ara mi.

"Emi ẹni oṣi! Tani yio gba mi lọwọ ara iku yi"? Ti a ba kepe Ọlọrun, On yio da wa lohun yio si gba wa.

## IDAHUN.

"Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa" Romu 7:25. "Nitorina bi Ọmọ ba sọ nyin di omnira, ẹ o di omnira nitotọ. Jesu ni idahun ohun gbogbo, eyi si ni idahun ibere rẹ. Ko si si igbala lọdọ ẹlomiran: nitori ko si orukọ miran labẹ ọrun ti a fi fun ni ninu enia, nipa eyiti a le fi gba Wa la bikoṣe orukọ Jesu Kristi. IṢE AWỌN APỌSTELI 4:12. Jesu nikan ṣoṣo lo le gba wa la kuro ninu ẹṣẹ wa. Ẹjẹ Jesu ti o ta silẹ lori igi agbelebu nikan lo nwẹ wa nu ninu ẹṣẹ wa. Ko si Oniṣegun, tabi ogun, tabi oṣo, tabi ajẹ, ko si enia tabi Oniwasu tabi ijọ ti o le gba

enia la ninu ẹṣẹ rẹ. A fi Jesu, Ọdọ Agutan Ọlọrun ti o ko ẹṣẹ aiye lọ nikan lo le gba enia la nipa Ẹjẹ Rẹ iyebiye ti o ta silẹ, ati nipa agbara Ẹmi ti ngbe inu Rẹ. Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun wa si aiye yi "lati la oju awọn afọju, lati mu awọn onde kuro ninu tubu, ati awọn ti o joko li okunkun kuro ni ile tubu". ISAIAH 42:6,7. Jesu wi fun wọn pe, "Ẹnikẹni ti o ba ndẹṣẹ, on li ẹru ẹṣẹ, ṣugbọn bi Ọmọ Ọlọrun ba sọ nyin di omnira, e o di omnira nitotọ" Johannu 8:34-36. Jesu ni otitọ na ti nsọ ni di omnira.

Jesu Ọmọ Ọlọrun ti ko gbogbo ẹṣẹ wa lọ ninu ara Rẹ lori igi agbelebu. A ti kan awọn ẹṣẹ rẹ mọ agbelebu. "Lotọ o ti ru ibinujẹ wa, o si gbe ikanu wa lọ, ṣugbọn a sa a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa, ina alafia wa mbẹ lara rẹ, ati nipa ina rẹ li a fi mu wa lara da." Isaiah **53:3-7.**

## "MO DUPẸ LỌWỌ ỌLỌRUN NIPASẸ JESU KRISTI"




## Ẹ NITI ỌMỌ [JESU] BA SỌ DI OMNIRA, YIO DI OMNIRA NITOTỌ [JOHANNU 8:36].

Barabbas jẹ ẹlẹṣẹ ati apania ẹniti wọn ti da ẹjọ iku fun. A nilati kan mọ agbelebu, ṣugbọn Jesu gba iya Barabbas jẹ, o si gbe agbelebu na ti a ba kan Barabbas mọ. Jesu Ọmọ Ọlọrun ni wọn kan mọ igi agbelebu

dıpo Barabbas, dipo rẹ ati dipo emi na, a da apania yi silẹ nitoripe ẹnikan ti ku iku rẹ. Iwọ ati emi ni Barabba na. Nitori iku li ere ẹṣẹ, ṣugbọn ẹbun ọfẹ Ọlọrun ni iye ti konipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa. Bi o ba fi ọkan igbagbọ wo agbelebu Kristi, iwọ yio ri ara rẹ kedere ati ẹṣẹ rẹ ti a kan mọ agbelebu. Jesu ti gba iku rẹ ku lori igi agbelebu ki iwọ ba le wa laye titi lai. Jesu ti ta ẹjẹ rẹ silẹ fun imukuro ẹṣẹ rẹ. Nitoriti Ọlọrun fẹ araiye tobẹ gẹ ti o fi Ọmọ bibi Rẹ kan ṣoṣo fun ni pe ki o ma ba ṣegbe, ṣugbọn ki o ba le ni iye ti konipẹkun.

Lẹhin ti Iyawo Ojoye yi ti gbọ gbogbo awọn ọrọ wọnyi, lẹsẹkẹsẹ o gba Jesu Kristi gbọ ni kikun, O si fi ọkan rẹ fun Kristi ẹniti o ti gba iku rẹ ku lori igi agbelebu, ti o si ta ẹjẹ Rẹ silẹ lati wẹ ẹṣẹ rẹ gbogbo nu. Obinrin fi ọkan ẹṣẹ rẹ fun Ọlọrun, Ọlọrun si fi ọkan titun miran fun, o si fi Ẹmi-Mimọ kun ọkan rẹ. Ki ṣe kiki pe boya Ọlọrun dari ẹṣẹ ji Obinrin yi ni kan, ṣugbọn Ọlọrun gba kuro lọwọ agbara ati ipa ẹṣẹ. Fun ọdun pupọ lati igba na ni Obinrin yi ti ngbe igbe aiye mimọ, igbe aiye iṣẹgun, igbe aiye ti ko ni eri ati abawọn. Obinrin yi ki mu biya mọ rara, ki mu siga, ki si mu taba, igbe aiye ọtun ni Obinrin Iyawo Ojoye yi ngbe ni ojojumọ. Igbesi aiye ti Obinrin yi bẹrẹ si gbe fi han dajudaju pe otitọ ni Jesu Kristi jẹ ẹda titun. "Ohun atijọ ti kọja lọ, kiyesi nwọn si di titun. II Kọrinti 5:17.

Iwọ Ọrẹ mi Ọwọnjulọ ti o nka iwe yi le di omnira loni yi nipa igbagbọ ninu Kristi Jesu. Jesu wipe "Wa si ọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ ti a si di ẹru wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin." Jọwọ wa si ọdọ Jesu nisisiyi gẹgẹ bi o ba tiri nibikibi iyowun ki o wa. Wa sọ gbogbo ibanujẹ rẹ fun Jesu, jẹwọ, jẹwọ gbogbo ẹṣẹ rẹ fun. Jesu ko ni ta ọ nu, bi o ba tọ wa pẹlu ọkan irẹlẹ ati iwariri.

Bọya o jẹ arugbo kan ninu I jọ, ṣugbọn ojojumọ ni o nṣubu sinu ẹṣẹ. Wa sọdọ Jesu loni yi, On yio si sọ ọ di omnira, ni ọna kan na ti O gba wo Adẹtẹ san ti o si la oju afọju. Jesu ko yipada, ọkanna ni, O si lagbara lati wo ọkan to gbọgbẹ san ati lati da onde silẹ lati inu tubu. Ẹniti o dari gbogbo ẹṣẹ rẹ ji ti o si tan gbogbo arun rẹ. Orin Dafidi 103:3.

Nigbati o ba ti fi ọkan rẹ fun Jesu, sọ fun ẹlomiran ti ẹniti o sọ ọ di omnira. Awa nihin pẹlu yio fẹ gbo irohin lati ọdọ rẹ wa.

J. R. Gschwend.

---

If you have found salvation in Christ, or have been otherwise blessed through our Gospel literature, please let us know. We would like to thank God with you, and remember you further in our prayers.

For **free** Gospel literature, books and tracts in over 540 languages, write to:

**E-MAIL: info@angp.co.za**

**ALL NATIONS GOSPEL PUBLISHERS**

**P.O. Box 2191, PRETORIA, 0001, R.S.A.**

(A Gospel Literature Mission financed by donations)

(Reg. No. 1961/001798/08)